AWON OHUN PATAKI NINU IWE OSE YI
IPADE NCNC
Oju iwe 1
Ijoba Ibokun
Oju iwe 2
E tonupiwada
Oju iwe 3
Ohun ta gbin
Oju iwe 4

# IRAHO ★ OBOKUN

Maşe pin Ijeşa
Oju iwe 5
Iforowero lori Ibusy
Oju iwe 5
Işelu tabi Ida'uro
Oju iwe 5
Iwe si NCNC
Oju iwe 7
James Adeşemi ku
Oju iwe 8
Ibironke selu Oyinbo
Oju iwe

Vol 4 No. 141 ILESHA MONDAY, JUNE 27 1955 IYE OWO TORO

## NCNC SE IPADE GBOGBOGBO NI ILESA: GOMINA AGBA NAIJIRIA DE



DR NNAMDI ASIKIWE
On ni Olori egbe NCNC ni ayipo Naijiria, O gba ijoba Ekun Iwo Orun tiyanju nipa oro Alafin.

## A TORO IDARIJI

O dun ni pupo pe işele nla kan, eyiti o koja agbara wa se idiwo fun wa lati gbe iwe irohin yi jade ni ojo ketala ati ogunjo oşu yi.

Nitori eyi a toro idariji lodo enyin Onibara ati Okawe wa, a si fi eleyi kewo lati fi la olukuluku loju pe idaduro koni si mo ni agbara Olorun.

OLOTU.



OLOLA OBAFEMI AWOLOWO
On, iyawo re ati opolopo awon aşaju egbe Action Group be Ileşa wo ni ojo satide to koja. A gbo pe ipade ni won wa se-

## GOMINA AGBA MIRAN TIDE

Lati igbati Olola John Macpheson, eniti o je Gomina agba fun gbogbo Nigeria tilo ni gbogbo enia ti nreti elomiran.

Ni nkan bi oşu kan abo sehin ni gbogbo enia ti nri ka pe elomiran yio de ninu oşu June.

Eni na ti gbogbo Naijiria ti nreti, Olola James Robertson KCMG, K. B. E. de ni ojo kedogun oşu yi si Eko.

Gbogbo awon olori (Premier) ijoba meteta lo lo pade Olola na lati ki kabo. Gbogbo awon minista ti ijoba akopo Naijiria lo wa nibe pelu.

Ni dede agogo kan osan na lo de ibujoko re, ni agogo marun irole ojo na logba ibura ni Kotu giga ni Eko.

Olola na ti ba awon oniwe irohin Naijiria soro ni ojo keji tode. Ni ipade na lo ti leri lati yi gbogbo Naijiria laipe. O so nibe pe Obabinrin ilu Gesi se ileripe on yio be Naijiria wo lagbara Olorun.

## IWADI ORO ALAFIN

Lati nkan bi oşu marun sehin ni ifimofele ti nkaiiri pe irohin iwadi oro togbodiyan Oyo ti jade. Tori oro iwadi na ni Alafin şeti Oyo sile

Eniti o wadi oro na, Ogbeni R.D. Lloyd sope Alafin ko jebi nitorina o ni kosi idi ti ko fi ni, lati pada si Oyo.

Şugbon Ijoba Iwo Orun Naijiria, lehin igbati won ti ka irohin na ti won si gbe yewo, won taku pe Alafin ko ni pada. Ni ojo kejo oşu yi ni a gbo pe won fun Alafin ni iwe pe won le ni Oyo.

Lati ojo ti iwe irohin iwadi na ti jade ni ariyanjiyan ti bere ni gbogbo ilu, larin ile, ninu iwe irohin nipa bi o ye sabi ko ye ki Alafin pada sile.

Awon onişe egbe işelu NCNC kan Oba na lara ni ojo kejidinlogun oşu yi lehin igbati won ti fi oro re ko gbogbo aiye lorun.

A gbo pe won ta loare.



SIR JOHN MACPHERSON
On ni GOMINA Agba fun Naijiria tele ri. Eniti won gbe wa si ipo re ti de. On na ni SIR JAMES ROBERTSON.

## IPADE N.C.N.C. TI EKUN IWO ORUN

Lati nkan bi ose meta sehin ni ikede ti njade pe egbe N.C.N.C. ni ayika Ekun Iwo Orun Naijiria yio se ipade gbogbogbo ni Ileşa ni ojo kejidinlogun oşu yi.

Ni ojo Jimo, ojo ketadinlogun oşu yi ni akowe N.C.N.C. fun eka Ekun Iwo Orun, Ogbeni Adebayo Asaya ti de si Ileşa.

Lati ojo na ni aşoju ti nde lati ibikibi ni Ekun Iwo Orun Igbati o fi ma di agogo mejo owuro ojo ipade na, ero to ti wo ilu Ileşa ti ju igba lo.

Ki ipade na to bere ni Gbongan Obokungbusi nibiti won ti pese sile fun ipade ni opolopo awon Minista ati awon N.C.N.C. to wa ni Igbimo ti Ekun Iwo Orun ati ti o wa ni igbimo akopo Naijiria lati Ekun Iwo Orun ti de.

Die ninu awon enia pataki pataki to wa si ipade

(Bere ni oju iwe 8)



OLOLA J. O. FADAHUNSI
On ni won yan ni akapo egbe NCNC ni ayika Ekun Iwo Orun.

## ANNOUNCEMENT

This is to announce to the general public that after the 25th of July 1955 the Office of the Ijesha Press Ltd will be removed from B 110 Okesha Street, Ilesha to the work-shop, B 149 Okesha Street, Ilesha.

Therefore all communications should be directed to:-

Ijesha Press Ltd.
P. O. Box 23,
B 149 Okesha Street,
ILESHA.



OLOLA D. K. OLUMOFIN
On na pelu ogunlogo awon asoju to wa si ipade NCNC.



ỌGBẸNI E. F. FADAHUNSI

On pẹlu awọn to ti fọrọwerọ nipa ibiti o yẹ ki ibusọ moto wa. Akọle Olotu keji sọpe aye wa fun ẹnikẹni Lati fọrọwerọ lori ibusọ wa nitori ki o le dara fun wa.

## IRẸPỌ ỌGA ATI ỌMỌ'DỌ

(Lati ọwọ Dadson Ajilore Ilesa)

Si ẹnyin ọkawe mi lọmọde ati lagba, lọkunrin ati lobinrin Mo ki gbogbo nyin pata pata Ọrọ mi yi ko ni pọ pupọ lori Irẹpọdun. Ọrọ na ni nipa Agbanisiṣẹ ati awọn Oṣiṣẹ.

### OṢIKA ỌGA

Opọlọpọ awọn ọga kekeke lo ma nfi iya jẹ awọn ọmọ-ọdọ ti o wa labẹ wọn. Iya ti awọn to gba wọn si iṣẹ ko le fi jẹ wọn ni nwọn yio ma fi jẹ awọn ti o wa ni abẹ itọju wọn. Iru eleyi ko dara rara.

Bi ọmọ-ọdọ ba ṣẹ ẹṣẹ kan ni OṢIKA ỌGA yio sọ pe on yio fi ẹsun rẹ sun ki wọn ta le le lọ: yio wa di pe ki ọmọ-ọdọ na ma bẹrẹ si fi owo be OṢIKA ỌGA na. Iru eleyi buru julọ nitoripe awọn alawọ funfun ki ṣe bẹ.

### IGBA OJO

Tani ẹni na ti ko mọ pe igba ojo jẹ igba kan ti a ko ni aye lati lọ ibiti o wu wa tabi lati lọ si ibi iṣẹ ni akoko ti o yẹ?

Opọlọpọ awọn OṢIKA-ỌGA lo ma nda awọn ti a fi si abẹ itọju wọn pada si ile nigbati wọn ko ba tete de ibi iṣẹ ni ọjọ ti ojo ba rọ ti ojo ko fun laye lati lọ si ibi iṣẹ ni asiko ti o yẹ. Iru eleyi na ko dara.

Opọlọpọ igba ni awọn wọn to de ibi iṣẹ ṣugbọn ani ẹniti o ma bere lọwọ twọn Ṣugbọn jẹ ki ọmọ-dọ kan de lẹhin agogo mẹjọ, ṣe ni oṣika ọga ma le pada lọ si ile. Iru iwa bi eleyi pẹlu ko dara.

### ỌGA RERE

Jesu gẹgẹ bi olukoni rere, a kọ gbọ ninu iwe mimọ wipe o ba ọmọ-ẹhin rẹ kankan ja ki o ma lu ni ẹṣẹ igba aya. Jesu ma ndari ẹṣẹ ji wa. sugbọn awọn oṣika ọga.wọn ki gbọ ẹbẹ. Iru eleyi na ko tun dara o. A si bẹ awọn olori gbogbo ki nwọn bawa bojuto awọn oṣka ọga wọnyi o,

O ṣeṣe ki awọn oṣika-ọga wọnyi pada di ọmọ-ọd lọdọ ẹniti wọn fi iya jẹ ri: tabi ki ọmọ wọn wa ṣe iṣẹ labẹ ẹniti wọn ti fi iya jẹ ri, nitorina ki ẹnyin oṣika ọga ni irẹpọ pẹlu awọn alabaṣiṣẹ yin o nitoripe Ẹda ko laropin bẹni ẹnikan-kan ko mẹhin ọla.

Akọle Olotu: Ẹ jọwọ ki ẹ maṣe kọwe yin ni inu-tẹhin mọ, ti ẹ ba kọ bẹ nigba miran ko ni rọrun lati gbe jade rara. Lẹhinna ki ẹ ma ripe ẹ fọwọ (sign) si iwe ẹsilẹ ọga ra ma rpẹ kiyin ti ẹ ba kọ tan: Ẹ ṣe o,

## IJẸṢA, O TO ASIKO LATI RONUPIWADA

(Lati Ọwọ Ọgbẹni Jcay Ọlalẹyẹ, Ebute Metta)

Inu mi yio dun ti Olotu iwe iroyin "IRAWỌ OBOKUN" ba le gba mi laye lati ba awọn Baba, Iya ati ẹgbẹ mi gbogbo ti a jijọ jẹ Ijẹsa sọrọ pataki ti o jẹ ẹdun ọkan fun mi ati ọpọlọpọ enia.

O jẹ ohun abuku ati iwa omugọ patapata, eyiti o si ti wọ ọpọlọpọ lẹwu lati ri pe awọn ọpọlọpọ ti wọn npe ara wọn ni ọmọ Ilesa ti ghadun lati ma pe awọn ti o ba ti jẹ ọmọ agbegbe Ilesa ni ara oko. Iwa omugọ ti o to e'e-yi ko si. Bẹni ti a ba fi oju inu wo, awọn ogunlọgọ enia ni o jẹ pe agbegbe Ilesa na ni wọn ti lọ si Ilesa. Ti Ọlọrun ba si ti gbọ adura wọn ti wọn lowo ti wọn si kọle si Ilesa, o dige ki iru awọn enia wọnyi bẹrẹ si pe ara wọn ni ọmọ Ilesa. Wọn a si gbagbe ilu wọn patapata.

O jẹ ohun iyalẹnu fun mi nigbati mo lọ sile laipẹ yi. Mo ba awọn kan pade nino moto ti mo wọ. Wọn nlọ si Imẹsi-Ile ni ọjọ na. Mo wọ moto wọn ni Ijẹbu-Ijẹsa de Ẹsa-Oke.

Awọn enia wọnyi wa bẹrẹ si ọrọ oṣelu-ko-ṣe-oṣelu ni sisọ.

Ibiti a ti nsọrọ yi ni ẹnikan ninu wọn bẹrẹ si pe ilu mi ni Ẹsa-Iṣu. Ṣugbọn mo wa wo titi ẹni-ti o nsọrọ yi papa Ẹjọrọ ni ilu on papa nitori mo mọ dele dadadara. Inu mi dun pe mo fun ni esi ọrọ rẹ bi o ti tọ ati bosi yẹ.

Idi ti mo ni lati fi ẹnu ba ọrọ yi nipe ẹniti o nsọ isọkusọ yi jẹ ọkan pataki ninu ẹgbẹ Oṣelu ti Ilẹ Ijẹsa.

Nitorina ẹnyin enia mi gbogbo ẹ fi oju inu wo, nigbati awọn t o pe ara wọn ni aṣaju nsọ isọkusọ bi eleyi, melomelo ni awọn ọmọ wọn ti ko mọ ile rara? Eyi ko tofo, eyi ko tofo fila imale ku pẹki.

Edekede ti wọn ni awọn aṣaju kan pe niyi ti wọn ni o nsa awọn Ẹkiti ya tiwọn lọtọ.

Iru ọrọkọrọ bayi na lomu ki Ẹfọn Alaye ati Imẹsi-Ile kuro lara Ijẹṣa titi di oni gẹgẹ bi mo ti gbọ.

Ẹnyin ara mi, ṣokoto gbọrọ ko ma dowo o. Bẹni a bimi l'Eko ko da nkan. Jesu Kristi ti a nsin loni, ileto kekere ni wọn bi. Bẹni ọpọlọpọ ninu awọn Oṣelu ilẹ Nigeria loni. Ileto na ni wọn bi ọpọlọpọ wọn. Eleyi ko to ironu fun awọn adelumalọ ti wọn pe ara wọn ni ọmọ Ilesa pe inu ikoko dudu ni ẹkọ funfun ti njade.

Nitorina ẹnyin ara mi ti a jẹ ọmọ agbegbe Ilesa, ọrọ niyẹn o. Onigba lo pe igba rẹ ni aikara ti wọn si ba fi kọlẹ. Awọn adamọ-dọmọ Ilesa ko jẹbi rara. Nigbati o jẹ pe awa ilu agbegbe Ilesa, ẹnu wa ko ko rara, ogo ni wọn ko pe wa lọmọ oko. Gbogbo owo ti Ijọba Ibilẹ Ijẹsa gbojule loni ti wọn ba da si ọna mẹrin mo ro pe owo awọn ti wọn npe lara oko yi nilati ko ọna mẹta.

Kini anfani ti wọn ṣe fun wa ninu owo na? Nitorina o to akoko fun awọn ilu gbogbo ni agbegbe Ilesa lati ji giri kuro ni oorun wọn atẹhinwa.

O si tun yẹ ki a ma dupẹ fun eto oṣelu tuntun ti wọn ṣẹṣẹ da silẹ, eyiti o fun olukuluku ileto ni ẹnu lori ọrọ ilu rẹ. O dami loju gbangba pe larin ọdun meji tabi mẹta si akoko yi, ara Ilesa na yio mọ dajudaju pe ko si oko nibi kankan mọ rara.

Ni ipari ọrọ kekere ti o si ṣe pataki yi, inu mi y'o dun ti awọn ẹniti iru iwa omugọ yi ba ti wọ lẹwu ba yi ọrọkọrọ ti ko ba iken gbe ti o wa lẹnu wọn pada. Mo si fẹ ki olukuluku wọn mọ wipe ti wọn ko ba pa iru iwa iyasọtọ bayi ti, pe ẹnikan ara oko, yio pẹ ki Ilẹ Ijẹsa to ni ilọsiwaju bi ti awọn ilu miran gbogbo. Gbogbo wa ni a si mọ daju pe ara oko wa larin ilu, bẹni ara ilu si wa nibiti wọn npe loko.

E MA KA

IRAWO OBOKUN

LOSOSE



J. M. AJAYI OBE

On jẹ ọkan ninu awọn meji to ṣe aṣoju fun Ilesa ni ipade ola ti ẹgbẹ NCNC ṣe si ọjọ kejidinlogun oṣu yi.

## OHUN TI ABA GBIN NI AO KA?

(Lati Ọwọ B. I. Timson (Ebute—Metta)

Mo gbe tana danu mo gbe omiran de. Inu mi yio dun ti awọn ọkawe Irawọ Obokun bale fi tọkan tọkan ka itan mi yi, ki wọn si fi ṣe ariko-gbọn, Awọn agbalagba lo ma nda weka na pọ.

Bi rere loba mọ- maṣe. Bi ka loba moṣe mura si. Atika atore ikan ko gbe o.

Nigba lailai, ọba kan wa ti o jẹ alakikanju, alagbara, ati jagunjagun. Ṣe ti ọmọde ba ni ohun ija lọwọ, o ma nro ni. Asiko ti ọba jagunjagun yi wa lori oye, ogun ko fi awọn enia rẹ ni ọkan balẹ rara.

Ọkunrin alagbara kan wa ni ilu ọba yi oruko rẹ a ma jẹ "At'ika, at'ore ọkan kigbe" T'ika t'ore kigbe jẹ alagbara ati jagunjagun. Kosi ogun ti o ma ba wọn lọ ti wọn ko ni ṣẹgun bọ. Ṣugbọn ti ọkunrin yi ko ba si nibẹ, wọn ma fi ẹsẹ wọn ṣe erupẹ wale ni. Ti o ba si ti ba wọn lọ gbo gbo ikogun, bi eru, owo, idẹ, ati aṣọ ti wọn ba ko wale, Tikatorekigbe yio pin si ọna mẹta apakan ti ọba, apakan ti awọn ọmọ ogun, apakan toku ti on alara ni.

Okiki ọkunrin yi kan ju ti ọba papa alara.

Nigbati o yẹ wọn bẹrẹ si di ọtẹ mọ ọkunrin yi. Ṣugbọn aṣeni nṣe ara rẹ, Ti wọn ba gba apa ọtun jade si, on na yio gba ti osi jade si wọn. Ti wọn ba gba ẹhinkunle wọ le, on na a gba ti ita jade si wọn. Ẹniti Ọlọrun ko ba pa, kosi ẹni ti o le pa,

Nigbati wọn wa ọna titi lati pa ọkunrin yi, ti wọn ko ri, ọba paṣẹ pe ki olukuluku awọn ọdẹ ba on wa ejo ọka ti o wa ni aye Gbogbo wa lo mọ ejo buburu yi. Ki ya ra san enia, ṣugbọn ẹkan ṣo ṣo ti o ba le bu enia jẹ ọrun ni ẹrọ rẹ.

Tikatore ko mọ kini kan, on k a n e b Ọ ọrun ti dani.

Ni ọjọ keji, ọkan ninu awọn ogboju ọdẹ ri ori ejo ọka kan gbe, osi gbe to ọba lọ. Oba dupẹ pe o ṣehun, o ni oni yi gan ni Tikatore yio fi aiye silẹ. Ṣugbọn epa npa ara rẹ o ni on npa aja. Ọba ni ki wọn ba on de ejo yi sinu igba funfun, ki wọn si gbe sinu apo ọdẹ. Ọba ranṣẹ pe Tikatore. Bi o ti yọ si afin ọba, ni ọba nki ni mẹsan mẹwa. Nigbati on ati ọba ki ara wọn tan, ọba yin i fun gbogbo iṣẹ rere ati igba-silẹ ti o ti nṣe fun ara ilu rẹ. Ọba ni "mo fun ọ ni ẹbun yi ṣugbọn maṣe tu ẹbun na nibi o, ti oba fi afin silẹ tan o le tu ẹbun na wo".

Tikatore si dupẹ lọwọ ọba laimọ ẹbun ti ọba fun on, o si kuro ni iwaju ọba. Bi o ti kuro ni ọdọ ọba tan, ọkan ninu awọn iranṣẹ ti o fi eti kọ ọrọ yi gbera o di ọdọ akọbi ọba gan. o sọ fun wipe bi iwọ ba bere nkankan lọwọ baba rẹ, koni fun ọ, odindi apo owo kan ni baba rẹ gbe fun Tikatore.

Kini ọmọ ọba na gbọ si? Koti lẹ ya si ọdọ baba rẹ ra ra. Ọna ile Tikatore lo ọ. Ironu ẹbun ti wọn gbe Tika tore ko jẹ ki o le rin rara. Kia ọmọ-ọba ti ba lọna.

Nigbati ọmọ-ọba de iwaju rẹ, o ni (Baba mi ọba ni ki emi lọgba ẹbun yẹn wa pito ri ko tọ siọ rara, ki o pada wa laro ọla ki o ma gba ẹb-un ti o tọ si ọ gan.)

Tikatore ko yi ni ohun pa da, o si bọ apo ti o gbe kọ apa; o gbe fun ọmọ ọba.

Inu ọmọ ọba na dun, nitori o ti fi ọgbọn gba apo owo ọwọ T'ika-t'ore. T'ika-t'ore si ba ẹna tirẹ lọ. Ọmọ-ọba ki yio rin ju ẹsẹ bata mẹwa ọ nigbati o ki ọwọ bọ inu apo na; o ba igba funfun ninu rẹ; njẹ ki on gbe apo owo ninu igba lo fi ọwọ gbe ọka ni iru. Bi iṣẹju akan ni ejo ọka bu ọmọ-ọba jẹ; o si ṣubu lulẹ bi ọgan; o bẹrẹ si japoro iku. Lẹṣẹkan-na ero ti pe le lori; wọn si bi lere wipe; kini ṣe ọ? Ọmọ-ọba na si da wọn lohun loju iku wipe, ẹbun ti Baba on gbe fun T'ika-t'ore ni on gba lọwọ rẹ; ti ejọ ọka si bu on san. Bi wọn si ti gbe ọmọ yi de iwaju baba

(Bere si oju iwe (6)



STEPHEN AKINBỌLAGBE

On je ọkan ninu awọn meji to je aṣoju fun ẹgbẹ NCNC ni Ẹkun Irepọdun. Ipade na yan awọn oloye ti yio ma ṣeto ẹgbẹ na ni Ẹkun Iwọ Orun Naijiria



ỌLỌLA S. O. AWOKỌYA

On ni Minista fun eto ikẹkọ ni Ẹkun Iwọ Orun Naijiria. Ninu iwe ti ọjọ kefa osu yi ẹnikan bere itumọ "including 10/6d Education and Medical Levy (Regional Share of Tax). O bere ohun ti wọn nfi ṣe ati awẹ n to nna. Ẹnikan ti dahun lọṣẹ yi.

# E KA NIPA IJOBA YIN

Wọn ni "bi egungun ẹni ba njo daradara, ori ẹni a ma ya" Irawọ Obokun lero wipe yio jẹ idunnu olukuluku lati ma ri irohin itẹsiwaju ka nipa igbimọ-ijọba akamọ tirẹ; nitoribẹ, a ti nṣe oriṣiriṣi atunṣe ni imurasilẹ lati ma ripe irohin njade ni ọsọsẹ nipa gbogbo awọn ijọba na.

Inu wa yio dun bi ẹnyin ọkawe wa ati aṣoju wa bi fọwọsowọpọ pẹlu wa lati ripe iṣẹ na rọrun ni ṣiṣe

Ọna ti ẹ file ran wa lọwọ nipe:-

A fẹ Aṣoju (Agent) ni ilu kọkan,

A fẹ aṣoju si ni Ileṣa.

A fẹ awọn ti yio ma fun wa ni irohin pipe.

A fẹ awọn Ọkawe kun awọn Ọkawe wa.

A fẹ ki awọn ti o mura tan lati ma ba wa ṣowo jẹ awọn ti yio ma sanwo lasiko.

Nitorina a nfẹ aṣoju ti yio ma fun wa ni irohin ati ti yio ma ta Irawọ Obokun ni awọn ilu wọnyi:- Ileṣa, Ibodi, Iperindo, Imẹsi Ile, Muroko, Itagun, Ipole, Igangan, Iṣẹ, Odo, Ilọba, Iwara, Erin Odo, Erin Oke, Ẹsa odo, New Ikeji, Old Ikeji, Isaobi, Ijẹbujeṣa, Etiọni, Ilerin, Ifẹ, Ibadan, Ọffa, Ikirun, Iragbiji.

## IWE GBANGBA SI ẸGBẸ N.C.N.C.

(Lati ọwọ Akọwe Afẹnifẹre)

Mo nfi iwe yi se kilọkilọ fun ẹnyin ẹgbẹ Akukọ pe ki ẹ dẹkun lati ma fajọngbọn. Lojojumọ ni ẹnyin nfẹ ki ilu daru.

O to akoko lati sọ fun yin pe akọwe yin ti ẹ npe ni Akindele Ojo, o to akoko fun yin lati da lẹkun gbogbo ikọkuko ati ọrọ isọkusọ ti o nsọ si ẹgbẹ tiwa ati awọn olori ẹgbẹ wa.

Bi ẹgbẹ Akukọ ba nfẹ ija ẹgbẹ Afẹnifẹre, ki nwọn tubọ ma kọ kabakungbe ọrọ ti Ojo nfi so wa nino. Awa ti mu suru de opin agbara wa n sisiyi.

Ẹ lọ ka Irawọ Obokun ti ọwọ yin ba tẹ, ki ẹ wo inu rẹ ẹ o ri pe ẹgbẹ wa ni Akindele Ojo mbu ni abufomiyọrun lọsọsẹ.

Kini ẹgbẹ Afẹnifẹre se ti Akindele Ojo fi npe ni ẹgbẹ Ọdaluru, ti o nfi ba orukọ ẹgbẹ wa jẹ? Kini ibi ti Awolọwọ fi se Ijẹsa ti Akindele Ojo fi nsọrọ itẹmbẹlu rẹ ninu Irawọ Obokun?

Kini Lawan on se? Kini Ajanaku se? Kini Ọyẹnilọye se ti ọmọ kan ti ko ni ẹkọ ilẹ yio fi ma se itẹmbẹlu wọn.

Akindele Ojo ti aye ninu Irawọ Obokun ti gbogbo Ijẹsa da silẹ lati ma ba orukọ awọn ti o fori la iku lati gbe isẹ na kalẹ jẹ. Fadahunsi alaga Irawọ Obokun lo gba Akindele Ojo laye lati ma ba orukọ awọn enia ilu jẹ, nitoripe nwọn ko si ninu ẹgbẹ Akukọ, ẹgbẹ onirọ, ẹgbẹ ibajẹ, ẹgbẹ ti ko fẹ ire ilẹ wa.

Awọn olubi ati olubajẹ enia ni yio sọ pe ibi ni Awolọwọ ati awọn ẹgbẹ rẹ se. Abaluje ati oloriburuku ni ko ni sure fun Awolọwọ ati ẹgbẹ rẹ. Kini Akukọ se fun wa? Kini Akukọ se fun Ijẹsa lọjọ arọ? O sepe fun wọn.

Akindele Ojo ti o nwa ọna lojojumọ lati da ilu ru, o tun npe ẹnikan ni ọdaluru, Fadahunsi na fun laye lati ma kọ ikọkuko na lọ.

Kilọkilọ wa ni pe bi Akindele Ojo ko ba sọrọ nipa ẹgbẹ rẹ, ko fi ẹgbẹ ti ẹlomi silẹ, a o jọ fi egun kan egun, a o mọ ẹniti o lagbara julọ.

Nigbati awa ba kọwe sinu Irawọ Obokun, Akindele Ojo ki ijẹ ko jade; sugbọn isọkusọ tirẹ a ma jade lemọlemọ lọsọsẹ.

Nigbati Akukọ gba igboro kankan ti Ijẹsa ko iti ri asiri eke wọn, ko si nkan ti awọn Akukọ ko tuwo nigbana. Afẹnifẹre ma suru, ko si idaluru. Nigbati awọn akukọ ge igi ọpẹ ti nwọn so mọ moto ti nwọn nwọ kiri igboro pe ọpẹ wọ, ilu ko daru nigbana. Nigbati araiyẹ ko iti ri idi asiri ẹtan wọn ti nwọn nke kakiri *Zeeeeek*! Zeeeeek! ẹrun ko ya lulẹ nigbana.

Sugbọn nisisiyi ti gbogbo Ijẹsa jadi irọ ati eke wọn, awọn ẹgbẹ Akukọ ti nwọn si nrọ wọ inu ẹgbẹ Afẹni*fẹre*, ti ori awọn Akukọ nfanyẹ yi, Akindele Ojo ni lati bẹrẹ puọ pe ilu ndaru, o ni lati ma wa ẹniti yio fi wẹ ori ninu ọrọ na.

Akindele Ojo ko bẹru Ọlọrun.

O ri ọna tara nilẹ o npurọ lati dari Ijẹsa sinu ọna odi.

Kini Ijẹsa ri gba lọdọ Asikue? Kini nwọn ti ri gba tẹlẹ ri? Kini nwọ nsi fun ro pe nwọn le ri gba nisisiyi ati lọjọ iwaju? Ofo. Ko si nkan ti a le ri gba lailai lọwọ ẹgbẹ Akukọ. Apo ara wọn ni nwọn njadu.

Nigbati nwọn ba nfẹ kẹ dibo fun wọn, nwọn mọ irọ pipa, ẹnu wọn si dun mọ eke, nwọn a se ileri gbogbo ilẹ a kun. Sugbọn nigbati nwọn ba wọle tan, nwọn a ma jijadu apo ara wọn.

Bi ko ba si elepe enia ati were ti ori rẹ ti daru, enia ko ni le mọ ijọba ti o nse rere fun wa ninu Akukọ ati Ọpe.

Akindele Ojo a ma sọrọ pẹlu Bibeli bi onigbagbọ atata. O gbagbe pe Esu papa a ma tọka si ọrọ inu Bibeli.

Adura ti o tọ si gbogbo Ijẹsa ni pe ki Ọlọrun gba ni lọwọ atannijẹ. Ki Ọlọrun gba Ijẹsa silẹ lọwọ ọdaluru ati awọn ọlotẹ ti nwọn ko le ri ire ninu gbogbo nkan rere ti Ijọba Afẹnifẹre nse.

Ewo ni Akukọ ti se ti a ti ri bayi?

Ẹmelo ni awa ọpẹ mbu Fadahunsi tabi Ibironkẹ, tabi Olowofoyeku tabi Awobiyi tabi Ilesanmi bi o tilẹ ti jẹ pe awọn lo nsi enia lọna to yi? Ẹmelo ni a nsọrọ ẹgan ati itẹmbẹlu si ọga yin Asikue?

Lakotan ọrọ mi yi, ẹnyin ti ẹ nkẹbọsi "Kiniun" nibiti ko si Kiniun, ẹ lọ kilọ fun Akindele Ojo pe kọ lọ fi opin si asikiye ati aroye isọkusọ rẹ ninu Irawọ Obokun. Bi o ba kọ sinu Pilot Asikue, ko ni bi wa ninu. Sugbọn ti ko ba siwọ ki ẹnyin Akukọ NCNC mọ pe rogbodiyan ti o ba bẹ silẹ, pe ẹgbẹ yin lo da silẹ o.

Ki ise ẹnikan lo ni ilu ati ilẹ Ijẹsa. Ki ẹnikan mase ro pe on yio ma bẹ awọn miran lailai iyọrisi kan.

Olotu ọrọ na wa lọrun rẹ papa ti o nfi aye gba ikọkuko ninu Irawọ Obokun.



E. A. ṢAJUYIGBE

On lo fun wa ni irohin nipa bi awọn Ibokun local council se nse ipade. O tun sọ nipa awọn ti ko mẹto ẹgbẹ ki wọn to fara bọ.



KANSẸLỌ D. ỌLA ỌṢUNLOYE

On ni Akọwe Ẹgbẹ Afẹnifẹre ni ilu Ilesa. O se kilọkilọ ninu iwe ọsẹ yi pe ti wọn ko ba kilọ fun Akindele Ojo ko mase kọwe nipa Ẹgbẹ Ọlọpe mọ, o ni bi bẹkọ "ao jọ fi egun kan egun, ao mọ ẹniti o lagbara julọ."



## Ikede Ati Ipolowo Oja Ninu "IRAWO OBOKUN"

OJU EWE KINI

| | | | |
|---|---|---|---|
| Igba | 1—12 | 8s. | fun insi kan. |
| Igba | 13—25 | 7s. 6s. | „ „ „ |
| Igba | 26—52 | 7s. | „ „ „ |

OJU EWE KEJI

| | | | |
|---|---|---|---|
| Igba | 1—12 | 5s | fun insi kan |
| Igba | 13—25 | 4s. 6d. | „ „ „ |
| Igba | 26—52 | 4s. | „ „ „ |

OJU EWE KẸTA

| | | | |
|---|---|---|---|
| Igba | 1—12 | 7s. 6d. | fun insi kan |
| Igba | 13—25 | 7s. „ „ „ | |
| Igba | 26—52 | 6s. 6d. | „ „ „ |

OJU EWE KẸJỌ

| | | | |
|---|---|---|---|
| Igba | 1—12 | 6s. | fun insi kan |
| Igba | 13—25 | 5s. 6d | „ „ „ |
| Igba | 26—52 | 5s. | „ „ „ |

OJU EWE 4, 5, 6, TI 7 JẸ OWO KANNA PẸLU TI OJU EWE KEJI.

## IPADE NCNC TI ẸKUN IWỌ ORUN

(Bẹrẹ lati oju iwe 1)

na ni Ọmọ'ba Adeyinka Oyekan, Ọgbẹni H. O. Davies, Ọlọla P. A. Afọlabi lati Ọyọ, J. O. J. Onya lati Asaba, J. O. Fadahunsi, Adegoke Adelabu, Kọla Balogun, J. M. Johnson, H. Omo Osagie, Olu Kọmọlafẹ, Oweh.

Awọn Ọgbẹni T. O. S. Benson, F. S. Mc Ewen, Dr. Sanya Ọnabamiro, Tunji Olowofoyeku.

Ni nkan bi agogo mẹwa ni wọn bẹrẹ ipade na wọn si pari rẹ ni nkan bi agogo mẹrin irọlẹ.

A ko mọ ohun ti wọn sọrọ le lori, ṣugbọn a gbọ nibi pataki pe wọn ṣe ipinu lori pa ti NCNC ni lati sa lati ripe Alafin Ọyọ pada si Ọ̣ọi A gbọ pe gbogbo NCNC lati awọn ẹka ti wọn ti wa ni ọrọ na ka lara.

Bi nwọn ti kuro ni ibi ipade na ni gbogbo ogunlọgọ ero lonile ati alejo lọ si ile Ọlọla J. O. Fadahunsi nibiti wọn ti pese jijẹ ati mimu silẹ de awọn alejo na.

Ero to ti wa ni ayika Gbọngan Obokungbusi yi ju ẹgbẹrun mẹwa lọ. Ẹgbẹ Obirin N.C.N.C. wa nibẹ pẹlu awọn onilu to nlu ilu ayọ fun wọn. Orișirisi awọn ilu to wa nibẹ ju ogun lọ Moto ayọkẹlẹ olowo iyebiye to wa ninu ọwọ ero na to ọgọta olukuluku pẹlu aṣia N.C.N.C.

Ọjọ ajọyọ nla ni ọjọ na jẹ ni Ileṣa: Lẹhin jijẹ ati mimu, eyiti ko gbaye u kati kan ni ogunlọgọ ero tun pada siwaju gbọngan Obokungbusi fun ipade gbangba.

Awọn to sọrọ nibẹ ni Ọlọla Kọla Balogun, Olu Kọmọlafẹ, J. O. Fadahunsi ati Adegoke Adelabu. Gbogbo wọn lo sọrọ nipa aidara to wa ninu kikọ ti ijọba Ẹkun Iwọ Orun Naijiria kọ fun Alafin Ọyọ lati pada sile.

Wọn fiye ogunlọgọ ero to wa nibẹ pe eto iṣejọba lọna ti ko bojumu ni awọn Ọlọpẹ fi nṣe ijọba. Wọn sọ fun ipade na bi ijọba Ọlọpẹ ṣe yọ Dr. Sanya Ọnabamiro kuro ni igbimọ to nṣeto nipa awọn to nkẹkọ ni ilu Oyinbo ni inawo ijọba nitoripe Dr. Ọnabanro lodi si eto ẹkọ ọfẹ ọmọ kekeke gẹgẹ bi wọn ṣe nṣe.

Wọn ṣe alaye fun ipade na bi ijọba Ọlọpẹ ṣe yọ Ọlọla Adegoke Adelabu ni Kanṣẹlọ ni Ibadan, wọn si fiye wọn iru itiju ti yi o mu ba wọn nigbati ara Ibadan ba da Adelabu pada sipo rẹ.

Wọn fi ye awọn ero na pe o lẹwu ti ijọba ba wa lọwọ awọn to nṣe bayi lo ida ijọba. Nitorina wọn bẹ wọn lati sa ipa wọn lọna to ba ofin mu lati ri pe Alafin pada si Ọyọ ati pe ni igba miran ki wọn ri pe jọba ko bọ sọwọ ẹgbẹ Ọlọpẹ mọ.



ỌGBẸNI J. J. IBIRONKẸ

On jẹ ọkan ninu awọn Aṣaju Oṣelu ni Ilẹ Ijẹṣa. O lọ si ilu Oba ni ọjọ kọkanlelogun oṣu yi fun eto ati itẹsiwaju iṣẹ rẹ. Ọpọlọpọ awọn ọmọ Ijẹṣa lo sin de idikọ ni Apapa.

## ALAGBA SAMUEL ADEYẸMI DI OLOGBE

Ni ọjọ kẹrinla oṣu yi ni okiki kan kakiri Ileṣa ati Ibokun pe Alagba Samuel Adeyẹmi di ologbe. Alagba na jẹ ipe Ọlọrun lẹhin igba ti o fi ṣaisan fun ọjọ mẹta.

Ki o to di ọjọ Wednesday ti i ṣe ọjọ kẹdogun oṣu yi ni ọpọlọpọ awọn ẹbi, ibatan, ọmọ ati ana ologbe na ti nde ile Ọgbẹni S. O. S Adedeji, eniti o jẹ Daodu Alagba na ko gba ẹṣẹ. Bi awọn abanikẹdun ti nwọle ni wọn njade.

Ni nkan bi agogo mẹrin abọ irọlẹ ni ogunlọgọ awọn olufẹ sin oku alagba na de ile ikẹhin lẹhin ti Alufa Ijọ Ọtapẹtẹ ti ṣe iwasu to wuni lori nipa iwa igbagbọ alagba na

Ọpọlọpọ awọn ọmọ Ile Ẹkọ Obokun High School pẹlu ti Ilesha Grammar School lo pẹlu awọn to sin Alagba na de ite.

Die ninu awọn to wa nibẹ ni awọn Ọgbẹni B.A. Adedayọ, E.A. Oriowo, E.O. Ayọọla, R.A. Awobiyi, E.A. Ọke, S.A. Ojo, S. Abioye. Ṣaọla, awọn ọmọloku ati awọn opo pẹlu.

## POLOWO OJA Re, Ki o si fi EDUN OKAN RE Sinu IRAWO OBOKUN

## AWỌN IBIRONKẸ LỌ SI ILU OYINBO

Awọn Ọgbẹni J J Ibironkẹ ati S. O. Ibironkẹ pẹlu awọn to wọ ọkọ oju omi to fi Apapa silẹ lọ si ilu Oyinbo ni ọjọ kọkanlelogun oṣu yi.

A gbọ wipe Ọgbẹni J J. Ibironkẹ nlọ lati lọ wo alafia awọn ọmọ rẹ mejeji to nkẹkọ ni ilu Oyinbo. Yio si fi eyi kẹwọ lati de ọpọlọpọ ilu Oyinbo lọhun fun eto ilọsiwaju iṣẹ rẹ.

A gbọ wipe yio to nkan bi oṣu mẹta ki wọn to de.



ỌGBẸNI E. O. AYỌỌLA

On jẹ ọkan ninu awọn to ṣe ajo pupọ nibi isinku Alagba Samuel Adeyẹmi ni ọjọ kẹdogun oṣu yi.

## IKEDE PATAKI

Eyi ni lati kede si gbogbo agbaiye pe lẹhin ọjọ karundọgbọn oṣu July 1955, ao ko ile iṣeto iṣẹ Itẹwe Ijẹṣa kuro ni B 110 Okeṣa Street lọsi B149 Okeṣa St. ni ile iṣẹ itẹwe.

Torina ki olukuluku dari iwe rẹ si :-

Ijesha Press Ltd:
P. O. Box 23,
B149 Okesha Street,
ILESHA.

## IFILO PATAKI

### Fun Awọn Onibara Wa

A bẹ olukuluku awọn Onibara wa ti wọn jẹ IJESHA PRESS ni igbese ki wọn ki o mu ni ọkunkundun lati jẹki igbese ti wọn jẹ ki o tete de ọwọ Ọlọtu Iṣẹ yi ni ipari oṣu June titi di ipari ọsẹ kini ninu oṣu July 1955, ki a ba le ni igbende nla ninu apakan iṣẹ yi ti o ti ku: